Tọ́jú Rẹ̀ fún Ìkẹ́kọ̀ọ́

Gé e, ká a sí méjì, kó o sì tọ́jú rẹ̀

PÉTÉRÙ

7 KÁÀDÌ BÍBÉLÌ

ÌBÉÈRÈ

A. Kí nìdí tí Pétérù fi bẹ̀rẹ̀ sí í rì?

B. Pétérù kò ní ìyàwó. Ṣé òtítọ́ ni tàbí èké?

D. Nígbà tí àwọn aṣáájú ẹ̀sìn sọ fún àwọn àpọ́sítélì pé kí wọ́n má ṣe wàásù mọ́, Pétérù àti àwọn àpọ́sítélì yòókù dáhùn pé: “Àwa gbọ́dọ̀ . . .”

98 S.K.

Ọdún tí a ko ìwé tó kẹ́yìn nínú Bíbélì

1 S.K.

Ó gbé ayé ní ogórùn-ún ọdún kíní sànmánì Kristẹni

4026 Ṣ.S.K.

Ọdún tí a dá Ádámù

PÉTÉRÙ

ÌSỌFÚNNI ṢÓKÍ Apẹja tó tẹpá mọ́ṣẹ́ ni Pétérù, ó wà lára àwọn tó kọ́kọ́ di ọmọ ẹ̀yìn Jésù. Pétérù wà lára àwọn méjìlá tí Jésù yàn láti jẹ́ àpọ́sítélì rẹ̀, tó túmọ̀ sí àwọn tí a rán jáde. Nínú ìwé Ìhìn Rere mẹ́rẹ̀ẹ̀rin, òrò tí Pétérù sọ pọ̀ ju ti àwọn àpọ́sítélì yòókù lọ. Jèhófà lò ó gan-an láti wàásù àti láti ‘fún àwọn arákùnrin’ rẹ̀ lókun.—Lúùkù 22:32; Máàkù 3:13-19.

ÌDÁHÙN

A. Ó bẹ̀rẹ̀ sí í ṣe iyè méjì.—Mátíù 14:28-31.

B. Èké.—Máàkù 1:29-31; Jòhánù 1:42; 1 Kọ́ríńtì 9:5.

D. “. . .ṣègbọ́ràn sí Ọlọ́run gẹ́gẹ́ bí olùṣàkóso dípò àwọn ènìyàn.”—Ìṣe 5:18, 27-29.

www.jw.org © 2011 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania